**LAKAYE ỌRỌ**

OJU Oluwa mbẹ lara awọn olododo, eti Rẹ si ṣi si igbe won. Oju Oluwa kan si awọn ti nṣe buburu lati ke iranti won kuro lori ile.

Awon olododo nke Oluwa si gbo, o si yọ won jade kuro ninu ise won gbogbo.


# Irohin Yoruba

NO. 777 — APRIL 27 — APRIL 3, 1960 — Kobo Meji (2D.)


**OWE**

ANJUWỌN ko ṣe wi lẹjọ ija ilara ko tan boro.

Agbalagba ti yio tẹ ilẹ tutu yio da omi siwaju. Igba ki i tọ lọ bi orere aiye ki i tọ lọ bi ọpa ibon.

# AJỌDUN GẸLẸDẸ ATI ẸFẸ ẸGBADO ABẸOKUTA DUN

IBARA, Abẹokuta.

NI ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kejidinlogun oṣu yi ni awọn Ẹgbado Abẹokuta ati agbegbe rẹ bẹrẹ Ajọyọ Ajọdun Odun "Ẹfẹ ati Gẹlẹdẹ" ni Ibara Omida Abẹokuta titi di ọjọ Ọjọbọ ti ṣe ọjọ kokanlelogun oṣu yi, ki ọjọ yi to pe gbogbo awọn ero idalẹ ti de si ile fun ti Ajọdun yi. Gẹgẹbi eto iṣedalẹ nwọn, etutu ṣiṣe ati 'Yemoja bibọ ni nwọn koko fi bẹrẹ. Lati oruganjọ ni ẹsẹ awọn Oniyemoja ti pe si "Ojubọ Yemoja" ṣoṣo, bi nwọn ti nse, ni nwọn nsọ ti nwọn si ngmu ọti amukara. Awọn onilu bata paapa ko dawọ ilu lilu duro titi ilẹ fi mọ.

Nigbati o di agogo' mọkanla aro koja iṣeju mẹdogun ni awọn Oniyemoja

WO OJU EWE KERIN



*Olubara Ibara ya Fọto pẹlu awọn Oniyemọja nigbati nwọn wa sure fun ni Afin rẹ*

## Onitiri gbe ẹjọ ti o pe Benson lọ si 'Privy Council'

EKO.

NI ọjọ Eti ti iṣe ọjọ kejilelogun oṣu yi ni Ọlọla Adetokunbọ Ademọla, Olori Adajọ Agba Kotu nla Apapọ Ijọba Naijiria gba ẹjọ Kotẹmilọrun ti Ogbeni T. O. S. Benson gbe siwaju awọn Adajọ Kotu Alagameta, pe on ko gba ẹbi ti Kotu kekere da on lori ẹjọ idibo ti Ogbeni Samuel A. Onitiri pe on pe ọna eru ni nwọn fi dibo fun on wọle Igbimọ Apapọ Ijọba Naijiria o si gba wipe Benson jare, o ni ki Onitiri lọ san ponun merindinlogosan ati sile mejọ (£176. 8s.) owo irinsẹ fun Benson.

Nigbati Ogbeni Onitiri ti gbọ idajọ yi ni o ba tun pe ẹjọ lẹsẹkẹsẹ pe idajọ na ko tẹ on lọrun, ni o ba tun fi pe ẹjọ Kotẹmilọrun si Kotu Gigajulọ (Privy Council) abẹ Ijọba Gẹẹsi ni ilu Oyinbo. Bi nwọn ba ti tun pari rẹ si ẹ o ma a gbọ o.

## Ẹlẹgun Orisa jo lu ina, Orisa daloju rẹ

IDI ARABA, Eko:

ẸRIN arin-takiti ni gbogbo awọn ero iworan rin tuka nibi ere ariya igbeyawo okunrin Hausa kan ti o njẹ Hasani Dogo laipẹ yi ni Idi-Araba nigbati Oriṣa Bori gun obirin Hausa kan ti o nje Asana Zaria lojiji, nibiti o gbe nfo soke, ti o nfidi jalẹ, ni o ba ṣubu sinu ina ẹran sere, o si fi idi jona.

Ohun ti o fa ariwo ati ẹrin arin-takiti na ki awọn ero iworan to tuka ni pe:- Nigbati ere ariya na bẹrẹ, ti ẹsẹ gbogbo awọn gbajumọ Hausa Idi-Araba pe ṣoṣọ sibẹ tan, awọn oni goje bẹrẹsi fa goje, awọn onilu nlu, awọn onijo si njo ijo ajokara. Bi ere ariya yi ti dun lo yungba ti gbogbo ero iworan si nrerin ni Oriṣa Bori ba gun Asana Zaria lojiji, o bẹrẹsi jo ijo oriṣa rẹ, bi o ti nfo soke, ni o nfidi jalẹ, ito si nwọ gburugbu jade lẹnu rẹ.

Nigbati awọn elere na ri i pe o nfẹ da agbo wọn ru, ni awon gende ọkunrin kan ba mu u ti nwọn rin fa mọlẹ pin-pin-pin, nwọn si rọra gbe e sẹhin agbo, nwọn si fi i silẹ nibẹ pe ki o ma a gba atẹgun titi ti Oriṣa Bori ti o gun un yio fi da loju rẹ. Lẹhin ọgbọn iṣeju ti nwọn ṣe bayi tan ni Asanu ba tun dide wuya lojiji nigbati Oriṣa Bori tun gbe e, ki awọn gende ọkunrin to debẹ lati ragambu rẹ molẹ, nibiti o gbe nja pitipiti ni o ba ti idi bọ ina ẹran sere, o si fi idi jona. Werewere ti Oriṣa Bori ti o gun un da loju rẹ, o si nikgbe Waiyo! Waiyo!! Whiyo!! ni awọn ẹlẹgbe rẹ ba gbe e, nwọn si fi ogi tutu pa ibiti o fi jona na fun un.

**WO**


Ilu awọn 0pitan loju ewe 5

Itan Iṣẹdalẹ ilu 'kirun lojn ewe 6

Irohin Ilẹ Yoruba loju ewe 7

Aworan Ajọdun Gẹlẹdẹ ati Ẹfẹ 8 - 9

Kadara Ẹda 11

Aworan Onitan 12

Itan Iṣẹdalẹ Illa Ọrangun di ọsẹ ti o mbọ

# Ọmọ Naijiria kan pẹlu iyawo rẹ ku si Lọndọnu

LỌNDỌNU.

NI ọjọ Aje ti iṣe ọjọ keji, dinlogun oṣu yi ni Ọgbẹni Josiah Adeniyi Ibikunle ẹni ọdun marundinlogoji, ti o jẹ oṣiṣẹ "Nigeria Railway" ati iyawo rẹ Oyinbo Jean ẹni ẹgbọn ọdun ku si Lọndọnu; yara ọtọtọ ni awọn mejeji ku si; ninu yara ti ọkọ ku si kun fun atẹgun oloro, iyawo si fi aṣọ bo ara rẹ de ẹhin ẹrun nibiti on na ku si.

Nwọn ti jijọ ngbe pọ ninu ile yi fun ọdun mẹsan, nwọn si fi ọmọ mẹta saiye lọ; ọmọbirin ti o dagba ju jẹ ọmọ ọdun mẹdogun eyi ti o tẹle e jẹ ọmọ ọdun mẹfa aburo wọn ọmọkunrin ti o kere ju jẹ ọmọ ọdun mẹrin pere.

# Jokodọla bẹ Olotu wo

EKO.

NI ọjọ 'Ru ti iṣe ọjọ kẹta oṣu yi ni Ọgbẹni Joseph L. Jokodọla, ọkan ninu awọn onibara iwe "Irohin Yoruba ti o wa ni Nsawam Ghana wa ṣe ibẹwo Olotu "Irohin Yoruba" ninu ile iṣẹ rẹ ni 5/7 Apọngbọn Street Lagos nigbati o mbọ wa si ile lati Oke-Okun.

Inu Olotu dun pupọ lati ri alagba yi, nitoripe nwọn ti ri ara wọn ọjọ na ti pẹ diẹ. Bẹna ni inu Ọgbẹni Jokodọla paapa dun lati ba Olotu pade lẹkan si i. Lẹhin ti nwọn ki ara wọn ti nwọn yọ mọ ara wọn tan ti nwọn si fi ọro jomitoro ọrọ. fun igba diẹ ni Ọgbẹni Jokodọla ba dagbere fun Olotu pe on nkọja lọ si ilu on Ogbomọshọ, on a si ṣe to oṣu kan ki on to pada lọ si Oke-Okun, ati pe on a si tun ya kesi Olotu ti on ba npada lọ.

## AKIYESI

Ẹnikẹni ti o ba mọ itan awọn Ọba ilẹ Yoruba, iba ṣe eyiti o ti ku ni tabi eyiti o si wa laaye, ki o kọ ọ sọwọ, tabi bi nwọn ti ṣe tẹ ilu kọọkan do tabi eyikeyi ninu itan iṣẹdalẹ Yoruba. A o si tẹ ẹ jade fun anfani gbogbo enia. Ẹ ku iṣẹ o.

OLOTU






Aworan okeyi ni apakan diẹ ninu awọn ti o lọ ṣe ere ajọyọ ajinde leti okun ni ọjọ keji ọjọ Ajinde

# Awọn oṣiṣẹ 'Kaduna Textile Limited' da'ṣẹ silẹ

KADUNA

NI ọsan ọjọ Ẹti ti iṣe ọjọ kẹdọgbọn oṣu ti o kọja yi ni awọn bi ẹgbẹta (600) osiṣẹ 'Kaduna Textile Limited' jumọ da iṣẹ silẹ, nwọn joko laiṣiṣẹ laseko iṣẹ lati fi ibinu wọn han awọn ọga wọn pe awọn ko faramọ didaduro-lẹnuṣẹ ti wọn da ọkan ninu awọn duro. Nwọn ni oṣiṣẹ na ti nwọn daduro wa ninu ẹgbẹ awọn oṣiṣẹ ti iye wọn jẹ ẹgbẹrun.

Ọgbẹni Thomas Hananiya, agbọrọsọ fun ẹgbẹ na ni edeaiyede ti wa larin awọn onisẹ na ati awọn oṣiṣẹ na. O ni ohun ti o fa edeaiyede na ni 'Iwa aibikita ti awọn onisẹ na nhu'. O ni ninu oṣu kọkanla ọdun ti o kọya yi ni awọn onisẹ gba lati ṣe ẹkunwo sile meji lori ponun kan dipo sile mẹta lori ponun kan ti nwọn bere fun.

Ọgbẹni Hananiya ni lẹhinti Ayọrisi Iwadi Igbimọ Mbanefo (Nbanefo Com. Report) ti jade; awọn onisẹ 'Kaduna Textile Limited' fihan dada ninu ọrọ ti nwọn sọ pe awọn ko ni sọ ẹkunwo na awọn ko si san owo ti atẹhinwa ti nwọn ti jẹ wo (arrears).

O ni awọn aṣoju awọn alabojuto-iṣẹ ati awọn aṣoju ẹgbẹ na si ṣe ipade kan ni ọjọ Ọjẹbọ ti iṣe ọjọ kẹrinlelogun oṣu ti o kọja ni ọganjọ. O ninu ipade na ni nwọn si ṣe ipinnu pe ki awọn oṣiṣẹ na fi awọn ikọ wọn mẹrin ranṣẹ si awọn alabojuto iṣẹ na lati wa sọ ẹdun ọkan wọn fun wọn. O ni nigbati awọn si ṣe bẹ ẹ awọn alabojuto iṣẹ na ko gbọ ohun ti awọn ikọ na wa ba wọn sọ.

### NWỌN DA HANANIYA DURO LẸNUṢẸ

Ọgbẹni Hananiya ni nṣe ni nwọn si da Ọgbẹni Thomas Abuja, ọkan ninu awọn ikọ awọn akikanju ikọ awọn duro. Nwọn ṣe awawi pe ko ṣiṣẹ rẹ. O ni ṣugbọn Ọgbẹni S. Thorpes, ọga awọn alabojuto iṣẹ 'Kaduna Textile Limited' ti o ṣenu fun awọn yoku alabojuto iṣẹ na sọ pe idi ti nwọn fi da aduro lẹnuṣẹ yatọ si ohun ti nwọn wi. O ni nigbati Oyinbo Alabojuto iṣẹ ni ki o lọ nu ẹrọ iṣẹ, ko si lọ ṣe bẹ ẹ.

Ọgbẹni Thorpes ni nigbati on ṣi pe e si ile iṣẹ on nipa ọran na nṣe n'o bẹrẹsi bu on ti o si njuwọ sihin-sọhun bi o ti nsọ asọ, o ni ko mọ iwa hu rara. O ni iye ti awọn nsan fun awọn oṣiṣẹ awọn ju iye ti Mbanefo sọ pe o tọ lọ. Oni ti awọn oṣiṣẹ ba pada sẹnuṣe awọn alabojuto iṣẹ yio ba wọn jiroro lẹsẹẹsọ. O ni ṣugbọn awọn ko ni gba Ọgbẹni Thorpes sẹnuṣẹ pada mọ rara. Awọn oṣiṣẹ na koi ti pada sẹnu iṣẹ wọn laseko ti a ntẹ irohin yi.

# Ọmọ-jaguda ti o ji pọnun kan wẹwọn ọdun mẹta

EKO.

LẸNULỌLỌYI ni Adajọ Kotu kan ju ọmọ-jaguda kan, Godwin Nwachukwu si ẹwọn ọdun mẹta nitoripe o jebi ẹsun ti awọn ọlọpa fi sun pe, o ji pọnun kan (£1) mọ obirin kan ti o njẹ Mary Abọlade lọwọ. Ẹjọ ti awọn ọlọpa ro ni pe, ni budo mọto bọọsi ni Alagomeji lẹba Yaba ni ọmọ-jaguda na ti yọ owo pọnun kan ninu apamọ Mary Abọlade.

# Disu gbe Muniratu ni iyawo alarinrin

EKO.

NI ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kẹta oṣu yi ni Ọgbẹni Shakiru Akinola Disu gbe Omidan Muyibat Abẹọ Agunbiade ni iyawo ni Gbọngan apesi ile-iwe 'Ansar-ud-Deen Alakoro School'. Alfa M. K. Gbajabiamila n'o ṣe isin igbeyawo na, o si sọ iṣẹ ti ọkọ iyawo ni lati ṣe fun iyawo ati eyi ti iyawo ni lati ṣe fun ọkọ rẹ gẹgẹbi ilana Ọlọrun.

Lẹhin ti nwọn kuro ni gbọgan apesi ile-iwe na, ni ọkọ iyawo bafi jijẹ ati mimu tẹ gbobo awọn alabaṣeyẹ ọjọ na ti nwọn tẹle e lọ si ile rẹ 11/13, Upper King Street l'Eo lọrun, lati arọ titi ile ọjọ na fi ṣu. Orisirisi ilu ni o pe si ibi aṣeyẹ na, ọpọlọpọ awọn alabaṣeyẹ ọjọ na si ni o jo ti ọjọ ti nwọn ko ni ri aye jo silẹ Aṣeyẹ ọjọ na dun o larinrin, irohin ko to afojuba ni.

Ọpọlọpọ awọn enia pataki pataki ni o pesẹ si ibi eyẹ na.

# ILU AWỌN OPITAN (10)

## Lati ọwọ J. O. Shoyinka Mushin

Ni kukuru nwọn lọ kẹẹ-kẹẹ-kẹẹ lori pẹtẹlẹ nigbati o ya, nwọn bẹrẹsi pọn oke, nwọn pọn oke yi to iwọn bi buso mẹta ki nwọn to de gongo ori oke na, arẹ ti mu olukaluku wọn, nṣe ni nwọn fẹhin lelẹ, nwọn wa ta harīha. Lori oke yi ni nwọn tun gbagbe sun si.

**Arogbonjogun Jaku Sinu Ọgbun**

Ebi ni o ta wọn ji lati oju orun, bi idan ni olukaluku ti dana nwọn si jẹun onjẹ nwọn ni ajẹtan yanan-yan-an. Nihin, nwọn tun fẹ ma a bọhunbọ. Agbọgbọnwọbiẹwu tun gba nwọn ni iyanju, nwọn tun bẹrẹsi tẹ siwaju. Nwọn ko goke mọ lọtẹ yi, nṣe ni nwọn tun nsọkalẹ lati ori oke, sere ti



J. O. SHOYINKA

★ ★ ★

ẹsẹ Arọgbọnjogun se, lati ori oke tente ni o yi ogbiri-gbiri de inu ọgbun, nihin ni awọn ẹlẹgbẹ rẹ fi ṣe awati si. O wa ku awọn mẹta lẹnu irin ajo wọn.

**Agbọgbọnwọ Daro Iku Arọgbọnjogun**

Agbọgbọnwọbiẹwu da a ni imọran pe, ki awọn ti o ku wa ni idakẹ jẹ fun iṣẹju meji ni iranti ẹni wọn ti o lọ jẹ ipe Oluwa lojiji. Gbogbo nwọn si dakẹ jẹ ẹ. lẹhin idakẹ jẹẹ yi, o bẹrẹsi wasu fun wọn o ni, ẹnyin ara mi ninu Oluwa, e maṣe banujẹ 'tori ẹni wa ti o fi wa silẹ lọ ri bẹ ẹ , nitoripe ọjọ kanna si ajule ọrun lojiji, ko le ṣai kọ la jọ wa si ile aiye, o si da mi loju pe a ko ni lọ lọjọ kanna, adura mi ni pe Ọlọrun ma jẹki a fi ọjọ ọlọjọ lọ, nwọn ni Amin.

Nko le ṣai sọ ọrọ diẹ nipa ẹni wa ti o jaku sinu ọgbun gẹgẹbi ẹ ti mọ, igbakeji mi ni iṣe, osi gbọ ofe mi jinna, emi gan na ni ngo mọ ọ lara julo nipa ipo rẹ t'o ṣofo larin wa. Njẹ ẹnyin ara mi, ohun ti mo wi ki a to kuro nile ṣẹ, tabi o ṣẹ? E jọwọ ẹ ma fi ọrọ ọrẹ wa yi sọkan nigbagbogbo, ki ẹ si ma a reti pe o jẹ ọkan ninu awọn akikanju ti o ja, ti o si ba ogun lọ. Ki ẹ si gbin in si ọkan nyin pe ajasiwaju ni ao ma a ja, a kọ ni i ja ajasẹhin lailai. Niti iwọ ologbe Arọgbọnjogun ẹni wa ọwọn ti o fi wa silẹ lọ, a fi ẹmi rẹ si abẹ itọju Oluwa, a ko ni gbagbe rẹ lailai, iro rere ni a o mu pada lọ si ile, ti awọn ẹbi rẹ o ni fi banujẹ pe o ku lori ofifo.

**ORIKI ARỌGBỌNJOGUN**

"Arọgbọnjogun ọmọ aka-raba, ara Inisa.ọmọ Oba-dudu-ẹkọrọ, ina njo, ogiri ko sa, abaiya titimbiri, o ba wọn ja nibiti o ti f'ẹfọ ṣankọ lana, abara m'ore je; ọkunrin sii-sii loru, bi o ba d'ọrun ọi o ṣ'ọrun rere o, jọwọ, ma j'ọkun, ma j'ekolo, ma ba wọn k'ẹle onimọ bo o ba d'ọrun. O d'arinnako, o d'oju ala, o di k'a rini firi k'ajoni, odigbere, o tun d'ọjọ miran ọjọ rere o". Gbogbo wọn tu-puru sẹkun. Bayi ni nwọn pari isin ikẹhin fun idaro iku. Arọgbọnjogun.

Nwọn mu fila rẹ ti o ṣibọ ati apo ti o gbe kọ ejika ti o jabọ, nwọn di i ru ọkan ninu wọn lati le fi han awọn ẹbi rẹ ti nwọn ba pada dele

**Ebi de, okunrin mẹta, ọgaja fọwọ mẹkẹ**

Ebi ọgaja-fọwọ-mẹkẹ wa bẹ wọn wo, lẹsẹkẹsẹ oju wọn ti ran'ko ọrọ Agbọgbọnwọbiẹwu ko wo wọn leti mọ, nitoripe ebi ki i wọnnu, ki ọrọ miran wọ ọ. Awọn mejeji wa pa imọ pọ, nwọn ditẹ si Agbọgbọnwọbiẹwu, nwọn fẹ pa a, ero ọkan wọn nipe, o fi ọgbọn arekereke tan awọn wa si ilu iparun yi ni lati le gbọla ati iyi nigbati o ba fi ebi pa awọn ku tan bamubamu. Ọrọkọ-rọ ti o wu ki Agbọgbonwọ-biẹwu baba wọn sọ nṣe ni nwọn nhan pọnkan. Ko binu o nfi ẹso ati ọgbọn ero ba wọn lo.

**Agbọgbọnwọ Pa Ẹran Fun Wọn Jẹ**

Gẹgẹbi ẹ ti mọ wipe Agbọgbọnwọ gbọ ọrọ awọn ẹranko, atipe o si le sọ ede siwọn pẹlu. O bẹrẹsi gbẹ koto ti o jin, nigbati o gbẹ ẹ tan, o rọra fi ewe gbigbẹ bo o lori, o si fi erupẹ furu oju rẹ. jagun tẹdimolẹ, o bẹrẹsi fọn ifọnkufọn bi erin, lọgan ni awọn ẹranko nla-la bi Ira ati agbanrere bẹrẹsi ṣe yọ lọnakọna, nwọn si mbọ wa si ọdọ rẹ, eyikeyi ti o ba ti ni ki on rekọja sọdọ rẹ, nṣe ni nwọn jalu koto wọ ọ. O ṣa, o rọ, o si fi awọn ẹranko yoku sinu koto nibẹ lati dibajẹ.

**Agbogbonwọ Bẹrẹsi Yan Awọn Ẹran**

Awọn alafebipa ọmọ ẹhin rẹ ti daku lọ gbadari, oorun ẹran ẹgbẹ ni o ta nwọn ji, koi ti i fi lọ wọn, ki nwọn to bẹrẹsi ya ẹran jẹ ni gbigbo-na, nwọn si jẹ ẹ ni ajẹyo.

**Akiyesi lọsẹ ti o mbọ, e o ma a ka apa (10) Olotu tirẹ a sunwọn o.**




# ITAN IṢẸDALẸ ILU IKIRUN

Lati ọwọ L.A.T. Okunẹyẹ 85, Aderẹmi Road, Ile - Ifẹ

OLOTU emin yio dupẹ bi e ba le gba mi aye lati sọ itan ilu kan pataki ti mo mọ ni ilẹ Yoruba. Itan na lọ bayi:-

Ilu Ikirun jẹ ibudo ọdẹ ni ipilẹṣẹ rẹ, oruko ọdẹ ti o si kọ pagọ sibẹ a ma a jẹ Obaṣẹntan, ara Ila ni okunrin yi, o si pagọ yi sibẹ fun simi lẹhin ti o ba ti igbẹ ọdẹ de.

Laipẹ lẹhin eyi, okunrin kan ti a npe ni Ọba-ara, ọmọ Akin-ọrun at awọn enia rẹ wa si ọdọ ọdẹ yi lati ba a joko, Ilari ni oruko ilu nwọn ti nwọn jade wa si ihin. Ọkunrin ọdẹ yi jẹ oninu rere pupọ, bẹni o si gba wọn towọ tẹsẹ; laipẹ Ileba ọdẹ yi bẹrẹ si kun, awọn enia bẹrẹ si ya wa lọtun ati losi Ileiba Ọdẹ na si tobi to ilu.

Nigbati Ọbaṣẹntan ọdẹ yi ri i pe enia npọ pupọ, o pe awọn ti nwọn jẹ olori.olori wọn jọ, na ni ki nwọn panupọ ki nwọn yan ẹnikan lati jọba fun wọn o niti ọn, on ko le raye toju ilu, nitori on ko le fi iṣẹ ọdẹ ṣiṣẹ silẹ; nwọn si yan Ọba-ara Akin-ọrun lati jọba le wọn lori oruko rẹ yi na ni o mu ni nwọn si tẹ mọ ọ lara, oruko rẹ ni yi na ni omu ki a ma a pe ilu paapa na ni "Ikirun",. tabi ilu Akin-orun, gbogbo awọn ti o si tun njọba lẹhin rẹ na ni a npe ni akin-ọrun, eyiti adape. rẹ njẹ "kirun" nisisiyi.

### AWỌN ARA ILU LAJULU ṢIGUNSI IKIRUN

Lẹhin iku Ọba-ara Akirun kini, ọmọ rẹ Gbọlẹru bọ si ipo rẹ, lakoko Gbọlẹru ni awọn ara ilu ilukan ti a npe ni Lajubu ṣigun lati wa ba awọn ara Ikirun ja, nigbati Gbọlẹru gburo wọn, ti o si ri i pe apa on ko le ka won, o ko awọn enia rẹ, o si salọ si ilu kan ti a npe ni Imẹkun, ṣugbọn ko pẹ lẹhin na ti wọn si tun fi pada si ilu wọn. nitoripe awọn ogun na ko pẹ ti nwọn fi ṣẹri pada kuro lọdọ wọn.

### ỌBA ADEDEJI KO KU, O KOLẸ NI

Ko pẹ lẹhin ti nwọn pada de Ikirun tan ni Gbọlẹru ku, Aiyemunijẹ si gun ori oye lẹhin rẹ, lẹhin ti Aiyemunijẹ ku Adedeji gori oyc, Adedeji yi ni oogun pupọ, atipe, bi o ti ni oogun to, nigbati o darugbo tan patapata, ko ku, wiwọ ni o wọlẹ.

### ỌBA FATOLU JAGUN KO ILU-ỌBA

Lẹhin ti Adedeji wọlẹ tan, ni Oluṣoṣun jẹ Akirun, nigbati oku, Fatolu gori oye, Fatọlu yi ni Akirun ti o kọ ṣigun, o ṣigun si ilu Ọba, o si ko o. Lẹhin iku Fatolu ni Oyewọle jọba, lakoko Oyewole yi ni ogun kan ti a npe ni "ogun koloko."

### ỌBO ILỌRIN FI OYEBODE JỌBA DIPO LALỌWỌ

Lẹhin iku Oyewọle, ni Lalọọwọ jọba, ṣugbọn ko pẹ lẹhin ti o joye ni awọn ilu kọ ọ. lakoko yi ni ilu Ikurun wa labẹ awọn ara Ilọrin nwọn si mu ẹniti nwọn fẹ dipo rẹ lọwọ, oruko ẹniti nwọn si fẹ yi a ma a jẹ Oyeọbde, nigbati nwọn de Ilọrin, oruko awọn mejeji ni Ọba Ilọrin si fi ṣe idajọ. o bere oruko eyi ti o wa lori oye nisisiyi, nwọn dahun, wọn ni Lalọọwọ ni, o si bere oruko eyiti nwọn fẹ fi joye nwọn ni, Oyebọde ni.

Lẹhinna ni o wa sọ fun Lalọọwọ pe, lọ fi oye silẹ, nitori ọla rẹ bi ọba ti lọwọ. Ati pe oyé ti ekeji rẹ ṣẹṣẹ bọ de ni, bi o si ti sọ bayi tan o ni ki wọn gbe Lawani ti o jẹ bi ade fun awọn ọba Ikirun kuro lori Lalọọwọ, ki wọn si fi de Oyebode lori, bayi ni a gba Ijọba lọwọ Lalọọwọ ti a si fun Oyebọde, lehin ti nwọn pada de Ikirun, Lalọọwọ lọ si Oṣhogbo ko si tun pada de Ikirun mọ titi ti o fi ku.

### OGUN JALUMI 1879

Ni igba aiye ọba Akirun Oyebode ni awọn ara Ibadan ja ogun Jalumi (1879) nigbayi si ni awọn ara Ibadan ti gba Ikirun kuro lọwọ Ilọrin. Oyebọde yi na ni o wa lori oye ni akoko ogun kiriji pẹlu, ati ni akoko ti awọn ara Ibadan fi Ikirun ṣe ile; ṣugbọn emi rẹ ko gun pupọ nitori awọn ara Ibadan da a laamu pupọ, nigbati nwọn purọ mọ ọ pe, o ranṣẹ abẹlẹ si awọn ara Ilọrin, aibalẹ aiya, ati ẹjọ ojojumọ ni o pa a, ati lẹhin iku rẹ, Ọla bọ sori oye.

### NWỌN PURỌ MỌ ỌLA PE, O NFẸ IYAWO ỌMỌ OGBORILẸFỌN

Ọla yi na ni nwọn ro ẹjọ eke mọ pe, on ni o ti awọn ara Ilọrin lati ba oyinbo ja ni ọdọ Ọtin, ati pe o fẹ obinrin Babalọla ọmọ Ogborieḷẹfọn, Balogun Ibadan, ẹniti iṣe oluwa rẹ lakoko na. Nitori ilu Amọna rẹ ni Ikirun iṣe nigbana; nitori idi eyi a mu u wa si Ibadan, nwọn si fi Akadiri jọba dipo rẹ, ni ilu Ibadan ni Ọla yi kusi. Akadiri ti o joye ni ipo rẹ ni o si mbẹ lori oye loni yi o.

Iwọnyi ni oruko awọn Ọba tabi Akirun.

### ORUKỌ ỌBA MOKANLA TI O JẸ NI IKIRUN

1. Ọba-ara 2. Gbọlẹru 3. Aiyemunijẹ. 4. Adedeji, 5. Oluṣoṣun, 6. Fatolu, 7. Oye-wọle, 8. Lalọọwọ, 9. Oyebode 10. Ọla, 11. Akadiri ẹniti o wa lori oye loni oloni.

Eyi ni Ipari itan ilu Ikirun.

" Olotu mo dupẹ aye ti e gba mi. Ọkọ ọba ko ni ṣa yi lẹsẹ o,


şile kan pere

ra pakẹti

'ASPRO'

TITUN yi




Pakẹti "ASPRO" titun yi wa fun tita nisisiyi nibikibi. Sile kan pere ni owo rira rẹ, koro egbogi "ASPRO" mejila ni o wa ninu rẹ. Nisisiyi, ẹnikẹni le ni "ASPRO" ni ipamọ sowọ lati ma a lo o ni gbara ti o ba ti ni OTUTU-IBA. O ko le mọ igbati OTUTU-IBA yio kọlu ọ tabi ebi rẹ. Mura silẹ. Ra pakẹti "ASPRO" titun oni şile kan loni!

'ASPRO' nda irora

OTUTU-IBA DURO




Aworan oke yi ni ti igbati awọn Igbimọ Ipinlẹ Iwọ-Orun lọ ṣe abẹwo oko agbẹ ti o wa ni Fashọla l'Ọyọ. Ninu awọn ti o duro nibẹ ni Oloye S. L. Akintọla ati Iyawo rẹ, Ọgbẹni Osadebay ati Alhaji Z. A. Ọpalẹyẹ ti nwọn nwo bi Ọgbẹni Joseph Adler ara Isreal nṣe itọju awọn ohun ọsin.

# IROHIN KAKIRI ILẸ YORUBA

## Ẹgbẹ Binukonu Parapọ sepade

IFẸ-ỌDAN.

NI ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kẹsan oṣu yi ni awọn Ẹgbẹ Binukonu Parapọ (ti o ti ya ẹgbẹ wọn kuro ninu Ẹgbẹ Ọyọ Parapọ) ti nwọn ko si nṣe ẹgbẹ oṣelu rara, ṣe ipade oṣoṣu ti nwọn ma a nṣe ni ilu yi lati kesi Ile-iṣẹ Minista Alamojuto Eto Idajọ-ododo Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun ki o da awọn Kotu silẹ lọtọ fun ilu Masifa ati Isundunrin ni agbegbe Ejigbo. Awọn ikọ ti o wa si ipade na le ni ọgọrun enia

Irohin ti nwọn gbọ ki nwọn to ṣe ipinnu na ni pe, wọn ranṣẹ pe Balẹ Masifa ati Asundunrin Isundunrin pe ki nwọn wa papọ mọ Kotu Ijọba Ibilẹ titun Grade "D" ti nwọn ṣẹṣẹ fẹ da silẹ ni Ejigbo gẹgẹbi alabaṣepọ.

Awọn ti o sọrọ ninu ipade na si sọ pe, eto pe, ki nwọn ya awọn abule meji na ti o jẹ ara awọn Ibudo Ẹgbẹ Binukonu Parapọ kuro lara awọn abule yoku, ko tẹ awọn lọrun rara

Ọgbẹni Joseph Adegbami, Olori Ẹgbẹ Parapọ na ti ṣe alaye tẹlẹ pe, gẹgẹbi eto atijọ, ọna mẹta ni nwọn ti da Ibudo Ẹgbẹ Binukonu Parapọ si bayi: Ifẹ-Ọdan Owu, Masifa Isundunrin ati Olla Oguro Isoko Aye, ṣugbọn laipẹ yi ni o gbọ wipe Ile-iṣẹ Amojuto Eto Idajọ-Ododo ko ni fẹ lati da Kotu kansilẹ ni gbogbo agbegbe mẹtala na.

Ọgbẹni A. Enilọla ti o tun sọrọ, da a ni imọran pe, o yẹ ki nwọn ṣe iwadi lọdọ Minista ti o ba wa ni idi amojuto eto iṣẹ na gan an ki nwọn ba le ri idi otitọ lati ọdọ Ijọba nipa ero na. O si tẹnumọ o pe, ki iṣe aṣa Ijọba lati ma a da oju ibere ti awọn ara ilu ba bere delẹ.

Ọgbẹni Yesufu Bamidele, ti o ti wa ni aye Aṣoju Igbimọ Ijọba Ibilẹ ni damọran pe, o yẹ i awọn abule m ejeji kọkọ ṣe ipade na lati mọ boya eto titun yi ni ọpọlọpọ ninu wọn faramọ ni, tabi nwọn nfẹ Kotu tiwọn lọtọ. Gbogbo ipade si fi ara mọ imọran na, nwọn si sọ pe ki awọn Ikọ adugbo mejeji mu ero ti nwọn ba gba wa si ipade ti igbamiran.

Ọgbẹni Adegbami si tun nfẹ mọ bi nwọn ti ṣe to aye ijoko awọn Igbimọ Iriju Ijọ baibilẹ Ejigbo si, ati iru aye ti awọn aṣoju Ẹgbẹ Binukonu wa ninu Igbimọ na. Aṣoju Igbimọ kan lati Isoko si ṣe alaye pe, bi nwọn ti ṣe eto ti ọdun ti o kọja ni o tun wa bakanna lọdunni, ko si si ohun ti enia le ṣe aroye lelori ninu eto titun ti nwọn ṣe lọdunni.

Ninu awọn Ikọ pataki-pataki ti o wa si ipade na ni awọn bi:—Adimula Ifẹ-Ọdan, Ọlọla Olla, Olowu Owu, Alakoso Isoko, Aṣoju Asundunrin Isundunrin, Logun Ifẹ-Ọdan, Ọbajio Ifẹ-Owan, Ọmọ-ọba Morẹnikeji, Ọgbẹni Ojo Ọlọla, Ọgbẹni M. O. Adebajo, Ọmọ-ọba Adedokun, awọn Ọgbẹni Akan, Ọlọnade, Aṣoju Igbimọ Ijọba Ibilẹ ati awọn aṣoju lati gbogbo ilu ati igberiko ti o wa ni Ibudo awọn Ẹgbẹ Binukonu Parapọ.



Aworan oke yi ni awọn Ẹfẹ nigbati nwọn nkọrin lori orule.

## Awọn Ọmọ Adebilẹ se oku Iya wọn

IGBAJỌ.

NI irọlẹ ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kẹwa oṣu yi ni awọn ọmọ Adebile ṣe oku iya wọn, ni ile Oloye Iloro, awọn ọmọloku na ni J. Ade Adebile, S. Adeniyi Adebile ati Iyaafin Bọla Fajorẹ, nwọn si ṣe inawo ita oku na ni irọlẹ ọjọ kẹta.

Ọgbẹni Josiah Agbe ṣe gudugudu meje nibi aṣeyẹ na ati Iyaafin Ibidapọ Fagbeule, inawo ọjọ na buaiya o le gongo, awọn ọmọloku na si fi jijẹ ati mimu tẹ awọn alabaṣẹyẹ na lọrun.

Awọn diẹ ti aye wa fun lati darukọ ninu awọn alabaṣeyẹ ọjọ na ni awọn bi Ọgbẹni Babalọla Adejokun, James Aiyepola, Moses Tajero, Emmanuel E. Ladele, J. S. Ajayi, Moses Oyewọle ati Jacob.

Ẹhin oku a dara o.

## Samuel rọ awọn oṣiṣẹ pe ki nwọn sowọlu ṣiṣẹ

ABẸOKUTA.

LENULỌLỌYI ni Ọgbẹni Olu Samuel, Akowe Ẹgbẹ 'General Workers' Union' ti agbegbe Abẹokuta rọ awọn ọmọ Ẹgbẹ 'Niger Soil Construction Workers' Union' ti nwọn ṣẹṣẹ dasilẹ pe ki nwọn ma a sowọlu ṣiṣẹ. O si tẹnumọ o fun wọn pe, laipẹ ọjọ ẹgbẹ on yio bẹrẹ si ba awọn alabojuto iṣẹ jiro. ro lori bi nwọn yio ti se san ẹkunwo owo-iṣẹ ti Igbimọ Morgan sọ pe o tọ lati san fun awọn oṣiṣẹ Ipinlẹ Iwọ-Orun.

## Adajọ sọ ọlọsa kan si ẹwọn ọdun mẹta

IBADAN.

NI ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ọjọ kọkandilogun oṣu yi ni Adajọ Kotu Ibilẹ Ibadan (Ibadan Grade 'A' Customary Court) sọ ọlọṣa kan Akinọla Alade ti o ngbe Oke-Offa ẹniti o ti lọ sẹwọn fun igba mẹrin ri si ẹwọn ọdun mẹrin fun ẹsun ile fifọ ti o lọ fọ ile awọn Ọgbẹni Oye Ogunwale ati P. O. Kehinde, o si ji oniruru nkan ti iye owo wọn jẹ adọta pọnun o din ṣile mẹfa abọ (£49. 16s. 6d.)

## Awọn danadana gba mọto lọwọ awamọto

ABẸOKUTA.

NI ọjọ 'Ru ti iṣe ogunjọ oṣu yi ni awọn ọkunrin mẹrin kan ti nwọn wọṣọ dada ba onimọto takisi kan ṣe adehun lati haya mọto rẹ LD8216 lọ si Aiyetoro; ni ẹkun Ẹgbado. Nigbati Onitakisi na gbe wọn de abule Idi-Ẹmi, buṣọ mejidinlogbọn si Abẹokuta ni nwọn ba da mọto na duro, nwọn si di onimọto na Raji Akanmu lọwọ mu, nwọn si yọ ibọn ilewọ si i pe ki o fi mọto na silẹ fun awọn bi bẹkọ awọn yio pa.

Bi ọkan ninu wọn ti na ibọn ilewọ si awamọto na ni awọn mẹta yoku bẹrẹsi wa kọkọrọ mọto ninu mọto na kakiri. Nigbati awamtọọ na ko fun wọn ni kọkọrọ ni nwọn ba bẹrẹsi lu u; nigbati nwọn lu awamọto na pupọ ni nwọn ba ju silẹ ninu agbara ẹjẹ ni nwọn ba gbe mọto salọ. Ọlọpa si nwa awọn danadana mẹrin na nwọn koi ti ri wọn.

## Adajọ ju alarinkiri kan si ẹwọn oṣu mẹta

IBADAN.

LAIPẸ yi ni awọn ọlọpa mu odaran kan, Daniel Okafor ẹni ọdun mọkanlelogun wa si iwaju Adajọ Kotu Ijọba Ibilẹ Oke-Arẹ (Oke-Arẹ Grade "B" Customary Court) fun ẹsun pe o nrin kakiri budo mọto Ibadan ni ọjọ kẹfa oṣu yi. Nigbati o si rojọ, ti o gba pe on jẹbi ni Adajọ ba fi sọ ọ si ẹwọn oṣu mẹta.



## Ọdaran taku sinu apoti, o ni on ko lọ ọgba-ẹwọn

[illegible]



Ọmọdekiorin yi ni o kere ju ninu awọn Oniyemoja. On ati Ere rẹ gba iyi, o gbẹyẹ nitoripe ere rẹ ni o darajulọ

# Ere Ajọyọ Gẹlẹdẹ Ati Ẹfẹ Ẹgbado Abẹokuta



Odo Araba nibiti nwọn ti nbọ 'Yemọja' Ẹnikan latiọwọ osi ni Iyaafin Tinubu Orẹji (Olori awọn Oniyemoja Ibara Abẹokuta) ẹnikẹta ti o wa larin ni Iyaafin Fatoki Ayinbọ (Agbole Asawo Ibara) iran nwọn ni ma WURE ỌDUN niwaju Yemọja.



## GẸLẸDẸ ẸFỌN



Aworan awọn Ẹfẹ nigbati nwọn nkorin yi agbo ka, ki nwọn to gun orule.



Awọn Oniyemoja [illegible]



Awọn Oniyemoja [illegible] Orisa nwọn, Ẹnikeji lati ọwọ osi ni Olori awọn [illegible] Tinubu Orẹji, [illegible]



**Aworan Olori Oniyemọja nṣe etutu iṣẹdalẹ ni idakẹjẹ leti Odo Araba.**



Aworan yi ni ti [illegible] Lalubu II Onibara Ibara ni [illegible] Ẹfẹ pẹlu awọn enia pataki pataki ti o pe Lati ọwọ Osi ni Ajẹlẹ Agba Abẹokuta, Ọba ni o wa larin Ẹnikẹta ni Ogbẹni Jakande (Woye Ibara)





**ỌLỌGBỌN ONIṢOWO NGUN RALEIGH**

Pẹlu Raleigh oniṣowo yi le ko ọpọlọpọ nkan tita. Ko gb'asiko rara, pẹlu irọrun ni yio ma gun u lat'abule d'abule. Ọpọlọpọ ni yio ma taja fun lojojumo. Nipa bẹ yio ma pa'wo pupọ.

**O GBỌDỌ** *gun Raleigh*

GBOGBO IRIN KEKE
**RALEIGH**
LOKO



*Ti idaraya nkọ o?*
*Ṣe nipa o ti gbọn eeri-inu nu ni o?*
*njẹ . . .*



**ta ẹdọki rẹ ji pẹlu ANDREWS LIVER SAL**




[illegible]

RA IYỌ
**ANDREWS**
**LIVER SALT** LONI!



[illegible]

# AWORAN ONITAN



# WNTV-WNBS

## Awọn Ẹlẹrọ Gbohun-gbohun ati ti Alaworan Naijiria fi idunnu ṣe ikede pe nwọn yio ṣi

# Ile - Owo Ẹrọ Gbohungbohun Kini ni Naijiria

**NI ỌJỌ AIKU TI IṢE ỌJỌ KỊNI OṢU KARUN ỌDUN YI**

**YI ẸRỌ GBOHUNGBOHUN RẸ SI:**

602 Kilocycles.
498 Metres ) Ni agbegbe Eko

656 Kilocycles
457 Metres ) Ni agbegbe Ibadan

# IROHIN LATI OKE-OKUN ATI OKE-ỌYA

## Adajọ sọ ẹniti o ji £18 sẹwọn ọdun kan



Eyi ni aworan igbati Sheikh Awad Muhammed Ahmed Adajọ-Agba eto Kotu titun de si Kaduna lati Kano lati bẹrẹ aye ipo iṣẹ rẹ titun ti o bọ si nibẹ. Adajọ agba na ni o joko ni ọwọ osi yi ti o nse iwadi ọran pataki kan lọwọ Mallam A. Sakik Abas akọwe kotu agba ti o duro ti.

CALABAR.

NI ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kẹrindinlọgbọn oṣu ti o koja yi ni Adajọ Kotu Kekere Calabar, sọ ọdaran kan ara ilu Ikot Ekpene, ti o wa lati Fernando-Po sẹwọn ọdun kan nitoripe o jẹbi ẹjọ ole ti awọn ọlọpa ba a ṣe.

Bi ẹjọ na ti ṣe lọ si ni pe ọrẹ ọdaran na kan ti ilẹgbona mba ja bẹ ọdaran na pe, ki o ọ ba on gba pọnun mejidinlogun (£18) lọdọ ẹnikan. Nigbati o si gba owo na tan, dipo ki o wa fi jiṣẹ fun ẹniti o ran an lọ gba a nṣe ni o lọ si ilu rẹ. Nibẹ ni awọn ọlọpa gbe ti ri i mu.

Ọdaran na sọ fun Adajọ pe on ko ni owo lọwọ rara, on si ti lọ fi pọnun mejidinlogun na ti ọrẹ on ran on lọ gba fẹ iyawo titun kan.

## Apẹlẹwọn kan ii bata gbe, o wẹwọn oṣu mefa

BAUCHI.

LAIPẸ yi ni Alkali Kotu Ijọba Ibilẹ Bauchi ju ọdaran kan, Sule Bauchi, ti awọn ọlọpa ṣe apejuwe rẹ pe "apẹlẹwọn" ni si ẹwọn oṣu mẹta, nitoripe o jẹbi ẹsun ti awọn olopa fi sun pe o ji ẹwu agbada kan ati bata ti apapọ iye owo mejeji jẹ pọnun meji din ṣile mẹrin (£1 16s.) gbe.

Nigbati nwọn sọ fun ọdaran na pe ki o ro ẹjọ tirẹ, o ni on ko ji awọn nkan na, ṣugbọn ọkunrin kan ti o njẹ Ali Misau ni o ko wọn fun on. Nigbati nwọn bere lọwọ rẹ pe igba melo ni o ti wẹwọn ri, o ni, bawo ni on ti ṣe le mọ iye igba ti on ti wẹwọn ri nigbati on ko ni akosilẹ? Ṣugbọn awọn ọlọpa sọ pe, o di igba merindinlogun tị ọdaran na ti wẹwọn ri.

## *Nwọn ri oku ọmọbirin kan gbe ninu ile-igbẹ Kaduna*

KADUNA.

NI ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kẹtadinlogun oṣu yi ni nwọn gbe oku ọmọbirin kan Omidan Bantalẹ Williams ẹni ọdun mẹdogun jade lati ile igbẹ ni agogo mẹrin idaji mọju. Iwe kẹrin Oyinbo ni ọmọ nka ni "Anglican Girls School". Awọn ti o mọ ọmọ na sọ pe nkankan ko ṣe e, ara rẹ ya dada ni ọjọ ti nwọn ri i kẹhin ki o to o ku yi. Nwọn si ti gbe oku rẹ lọ si Inkuinku ile iwosan fun ayẹwo.

## Ole apẹlẹwọn tun wẹwọn oṣu mẹsan

UYO.

LẸNULỌLỌYI ni Ọgbẹni O. nko-Tariah, Adajọ Kotu Ijọba Ibilẹ Uyọ sọ Ubagba Akpan, ẹni ọdun 'apẹlẹwọn ọdaran kan, mejilelọgbọn si ẹwọn oṣu mẹsan: nitoripe o jẹbi ẹsun ti awọn ọlọpa fi siwaju rẹ pe o fẹ lọ fọle Ọgbẹni Asuqo Udo Ikpe ni ọjọ kọkanlelọgbọn oṣu keje ọdun ti o koja yi ni Ibiaku Uruan, Uyo, o si ji i ni ibọn oloju meji kan (Double Barrel Shot Gun) Nọmba 2379 ti owo rẹ jẹ ogoji pọnun (£40). Awọn ọlọpa na si tun ṣe alaye fun Adajọ pe ọdaran na ti lọ si ẹwọn ri lẹmeje, ni o ba fi tun sọ o sẹwọn oṣu mẹsan.

## *Enia marun ri sinu omi-odo*

KALABA.

NI ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ keji oṣu yi ni awọn enia marun, Iyaafin Mayo Etim ati ọmọ rẹ, ọmọ oṣu mẹfa; Edem Etim; Bassey Udoh ri sinu omi odo. Aboyun kan wa ninu awọn enia marun na ti nwọn ri.

Bi nwọn ti nwọ ọkọ wete kan lọ Kalaba lati ilu Kreek ni ojo nla kan bẹ silẹ lọjọ na ti aara si bẹrẹsi san, atẹgun pẹlu aara soju ọkọ wọn de, awọn enia mararun ti nwọn si wa ninu ọkọ na ba ri sinu omi odo, nwọn si ṣe ofo ẹmi wọn.

## Alaibikita awamọto wẹwọn oṣu mẹrin

MAIDUGURI.

NI ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ọjọ kọkandinlogun oṣu yi ni Adajọ Kotu Ijoba Ibilẹ Maiduguri ni ki ọdaran kan, Ali Yẹrima, ẹni ọdun mejidinlogoji lọ ṣe ẹwọn oṣu mẹrin: nitoripe o jẹbi ẹjọ ti awọn ọlọpa ba a ṣe pe o wa mọto kan ni iwakuwa o si nsun nigbati o nwa a.

# KADARA ẸDA

(Lati oju ewe kokanla)

lọ awọn le padanu. Nipa bayi, nwọn o ma a to ọrọ ati owo jọ, nwon o si maa ṣe bi ẹniti ko ni ohunkohun. Ipọnju ati aini gan an ni iru eyi ma nyọrisi, nitoripe lojiji ni nkankan yio ṣelẹ, yio si gbe gbogbo ohun ti nwọn ti fi pamọ, ṣugbọn ti nwọn ko lati na ninu rẹ lọ, nwọ a si di alaini.

Ẹ kiyesara ṣa o, nko sọ pe ki ẹ ya oninakuna rara—ẹ nilati ma a ranti itan ọmọ oninakuna ti a ri ka ninu Bibeli. O tete gba ogun ti yio jẹ tire ninu ohun ini baba rẹ lọjọ aiye rẹ, o salọ kuro nile o si lọ na gbogbo ini rẹ ni inakuna. On iba si ku sinu oṣi bikoṣe baba rẹ na ti o foriji iwa aimọkan rẹ ti o sira a pada lowo iparun.

Nitorina maṣe na inakuna, ma si ṣe ya omugọ ati amusua. Nigbakigba ti owo ba wọle funọ, botilẹ jẹpe o ya a ni, dupẹ lọwọ Ọlọrun fun owo na, fi ibukun si i ki o sijẹ ki o jade lọ; ma na owo l'aisi ibẹru tabi ifoiya, o ko si ni kabamọ l'aiye rẹ.

AWỌN NKAN YIOKU

O tun ku ọpọlọpọ nkan ti mo fẹ fi ye nyin ṣugbọn o si di igba miran. Ohun ti o ku ti mo fẹ fi ye ọ nisisiyi ni diẹ ninu awọn iwa wa ti o ma ndi ọna ibukun wa lọwọ.

Bi enia ba fẹran lati ma ṣe nkan ni abọ-abọ, tabi lati ma ṣe nkan ni aṣeti nigbati aye mbẹ lati ṣe e ni aseyori, dajudaju ibukun rẹ yio ma wa ni abọ-abọ tabi ni awa-tipọn bi o ba fẹran lati ma pa irọ tabi lati ma ṣeleri ti o ko muṣẹ, ọpọlọpọ igba ni ireti rẹ yio ma jasi asan. Bi o ba saba nfi pẹlu oju riro tabi pẹlu oṣe fi ẹbun torẹ, tabi o ko ma fi pẹlu ara yiya na owo, ibukun yio ma wa sori rẹ lọna ti ko te ọ lọrun. Bi o ba ni inu lile, ti o ko nforiji ẹniti oba ṣẹ ọ, tabi ti o fẹran lati ma a yan odi ati lati ma di enia sinu, awọn iwa wọnyi yio ma dina ibukun rẹ.

Ki alafia ki o wa pẹlu rẹ.

KOI TI PARI



Alapata ti o darajulọ nlọ si Banki ti o darajulọ.

BARCLAYS BANK D.C.O.

Iwọ, paapa, le bẹrẹsi fi owo rẹ pamọ sibẹ loni,

## AKIYESI FUN ONKAWE

Eyi ni lati sọ fun nyin pe, ẹnikẹni ninu ẹnyin onkawe ti o nkọwe si Olotu Iwe Irohin Yoruba ti ko ba fẹ ki iwe on sọnu ki o maa kọ ọ taara si ile iṣẹ rẹ ni:

Amalgamated Press Ltd.,
5/7, Apọngbọn Street,
P. O. Box 163, Lagos.

